**U. T. C.**
DEPARTMENT STORE
SERVES
**YOU**
**WELL**

**ELETI OFE**
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fiwe yi ṣe ikede si awọn Aṣoju iwe irohin Eleti Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, ẹnikẹni ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranṣẹ si wa, ao pe lejọ, ako si ni fi iwe irohin ranṣẹ si enibẹ mọ.

VOL. XI No. 627. LAGOS, SATURDAY, ~~MAY~~ JUNE 6, -JUNE 12, 1959. KOBỌ MEJI (2d)

# Isinku Ologbe Adajo Olumuyiwa Jibowu

A ro si ẹtọ lati so iba itan diẹ ti a ri gbo nipa Ologbe Adajọ agba Sir Olumuyiwa Jibowu fun enyin ọkawe wa. A bi ni ọjọ kedọgbon oṣu August, 1899.

Nigbati o pari ẹkọ iwe rẹ ni Ile ẹkọ giga tilu Abeokuta (Abẹokuta Grammar School) o si ṣiṣẹ oluko ninu ile ẹkọ fun igba diẹ, nibẹ lo ti gba iyi ipo ọla keji ninu ọdun 1922. O gb'oye nla B C.L. ninu ọdun 1923, nigbana lo wa gb'oye iṣẹ amofin.

O tun ṣe idanwo oye nla M. A. (Oxon) o si yege ninu ọdun 1957, irawo rẹ njo geregere ninu iṣẹ amofin nilẹ Nigeria titi di ọdun 1931, ti o gba iṣẹ Adajọ kotu kekere. O mọ orin kikọ pupọ nitoripe o j'ogun rẹ ni lati ọdọ Ọlọla baba rẹ Ọgbeni S. A. Jibowu Oloye F. I. G. C. M. L. Mus V.C. M. (Lond.) on si ni ẹni akọkọ to gba ipo adajọ kotu kekere ninu enia dudu ilẹ Nigeria.

### ISINKU OLOGBE OLUMUYIWA

Ninu Gbọgan iranti Gomina Goloba, (Glover Memorial Hall) l'Ehingbẹti ni ọjọ Alamisi ọjọ kerin oṣu June 1959, Eko, ni nwon tẹ oku ọlọla Sir Olumuyiwa Jibowu si, ti aimoye awon enia lọkunrin lobirin nrọ lọ bu ola ikẹhin fun u. Awon ẹgbe amofin (Lawyer) to pelu ẹwu oye won titi lọ de Ṣọṣi Berefutu ti nwọn ṣe isin ikẹhin ikẹhin fun oku Olumuyiwa, ese kogbeji ninu ile isin na.



OLUMUYIWA JIBOWU

Nigbati nwọn ngbe losi ibi oku ni Ikoyi, gbogbo Ọpọpo ọna mọto lati Ṣọṣi Berefutu titi lọ de Ikoyi, ko si ọna fun mọto kan lati koja.

Nigbati koke oku ti de Campos a gbọ wipe awọn enia koiti jade tan ninu Ṣọṣi. Awọn ẹgbẹ akorin lo ṣiwaju, Y.M.C.A. tẹle, lẹhinna awọn Sea Rangers, Girl Guides, Red Cross, awọn ọmọ ilewe, awọn enia nlanla ati enia pataki-pataki tẹle wọn

Bi nwọn ti de ni awọn enia lọ lọtun ati losi lati woran. Alufa DR J. O. Lucas lo se isinku rẹ.

Diẹ ninu awọn gbajumọ ti o wa si ibi isinku rẹ ni Gomina agba ati Iyawo rẹ, Gomina ... ati Iyawo re Sir Kofo ..., Oloye Ọbafemi Awolowo ati Iyawo rẹ, Oloye Akintola Sir Ralf Grey, Oloye F. R. A. Williams, DR. Akanni Doherty Alhaji Hedges, Oloye Rosiji ati awọn Ministers. Ododo (wreath) ti nwon fi se ibẹ loso fere ju ogun lọ.

## OJO TI O RO NI ACCRA FẸ GBE ỌMỌ LỌ

ACCRA Irohin kan wa wipe ojo ti o rọ arọ aida pẹlu oji fere gbe ọmọ kekere kan lọ, ọpẹlọpẹ oyinbo onimure kan ti o nkọja lọ ninu mọto rẹ s'ilu Nkawkaw ti o gbọ igbe ọmọ na ni o yara da mọto duro l'o fo silẹ sare lọ gba ọmọ na lọwọ agbara tofi di odo ti o ngbe ọmọ lọ. Ki Oluwa sọ wa lọwọ apọju ojo.

### O DI ỌSẸ TO MBỌ

Lọsẹ tokoja ninu iwe wa ni a sọ wipe ao berẹ si tẹ ede Hausa jade ni ọsẹ yi, ṣugbọn idiwọ iṣẹ ni ko jẹ, yio jade l'ọsẹ ti o mbọ lagbara Edumare.

Olotu.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Througout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
F. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

### Coal Handling Plant

Tenders are invited for the purchase of Coal Handling Plant at present located at the Abeokuta Power Station.

The specifications of this plant are as follows:-

(a) Length of ropeway ,, ,, ,, 513 yards
(b) Carrying capacity ,, ,, ,, 2 1/2 tons
(c) Buckets (size 2'3" x 1'10 1/2" x 1'5" depth) 10 No.
(d) Average ground clearance ,, ,, 17'6"
(e) Towers ,, ,, ,, ,, 6 No.
(f) Spacing of towers ,, ,, ,, 85'
(g) Plant driven by 3HP motor and driving gear in good condition

On payment of a deposit of £5 at the Electricity Corporation of Nigeria Headquarters, 13, Broad Street, Lagos, or to the Engineer and Manager, Abeokuta, arrangements will be made for inspection of the Coal Handling Plant.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential Tender for Coal Handling Plant" and must be received at the Office of :-

The Secretary,
Electricity Corporation of Nigeria,
Electricity Headquarters,
13 Broad Street,
Private Mail Bag 2030,
Lagos.

not later than noon on Saturday, 6th June, 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.

On receipt of a bona fide tender, the deposit of £5 will be refunded The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.

**ARTHUR FAUL**
Secretary to the Corporation

## MO NWA QKQ LATI FE

Olotu,
Jowo ba mi fi oro yi wẹlo boya ngo ri Okọ atata nipa iwe irohin rẹ.

Salamotu Aniwura ni orukọ mi, mo ti ba won ṣe dunia sugbon ko pe mi, mo ni owo lowo funra mi, mo ni awon aṣo ti mo fi nya won. Mo ni golu, mo si ko ile funra mi, iba ohun ti nje mi niya nipe nkoiti bimọ.

Mo ti bere si ṣe ẹsin, mo nfẹ lo si Mẹka, ṣugbon nko fe lo laijẹ pe, emi pelu oko lo lo.

Nitorina mo nfe Alufa tabi Alhaji ti koiti niyawo nile, ti yio si kapa okanjuwa re lati fi ara rẹ jin fun emi nikan eniti ko ni iya, ki o si ha mi ni ẹha.

Ẹniti o ba le ṣe, ki o kowe si Sala Aniwura, c/o Olotu Eleti-OFẸ, 28, Kosoko Street Lagos, ẹniti o ba wu mi ni ngo da lohun.

## QLQPA MU ENIA MẸFA

KANO. Awon enia mẹfa ninu omọ ẹgbẹ action Group nilu Gwaram ni a mu wa siwaju Alikali agba nigboro Kano ni ọsẹ to kọja, nwon di won ni ọwọ mọ ọrun won.

Ẹsun ti nwon ka mo won lẹsẹ ni wipe nwon se ipade laigba aṣẹ, nwon si fi abuku kan Ọba Jingunnu. Alikali Kano dahun pe awon enia na jẹbi Bulala. Nitorina ki a na ẹnikan ni ọgọrin bulala, ki a si fi won si ẹwon odu meta-mẹta.

Gbogbo awon enia na lo taku pe awon ko jẹbi, nwon si ngbe ẹjọ won lọ si Kaduna. Boya nwon le na won ni bulala na lọsẹ ti o mbọ ninu ọgba ẹwon ilu Kano.

# Ife Ni Akoja Ofin

Ọkunrin kan ti o ti ya ẹhanna sinu igbe ri awon enia meji ti nwọn wọ aṣọ ti nwọn mbọ wa, gbogbo irun ara rẹ dide, lati ba wọn ja.

Ijọba ti mọ pe inu iho apata ni ọkunrin to ya ehanna yi ngbe, nitorina nwọn fi ilẹkun irin se e mo ki o ma ba ja wọ ilu.

Nigbati awon meji na de enu ilẹkun, ọkunrin ẹhanna na muralati ja, o si fẹ fi agbara fa ilekun irin na ya.

Ọkan ninu awọn okunrin na towo bo apo osi fa ibon rifofa yo eyi ni ibon ilewo o wi fun ekeji re pe, mase sa fun u, ṣugbon ki o fi ife han a, o daju pe ori re yio wale.

Ọkunrin keji si rin s u n m o okunrin ehanna na, o wipe iwo ore mi, emi ko wa lati ja, o ri i, ko si ohun kan lowo mi.

Ọkunrin ẹhanna wi fi okunrin keji ti o mba soro pe, bi o ba je pe lotito ni iwo feran m i nje silekun fun mi ki njade tabi ko wo ile to mi wa.

Ibe ni okunrin keji ti taku o wipe, nitoto ni mo n i ifẹ s i e sugbon nko le wole t o o wa beni nko le si o sile.

(Wo yoku loju ewe kẹjo)

## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajẹla ọmọde agbọmola bi orisa, akọkọ lukọ ogun ti ndamọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti npa o tutu rẹ warawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abi u di ikugbagbe, o ṣ'ọmọ ti nhehin l'ore, Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri d'ẹkun iyọnu Olugbala f'ọmọ ti nyagbẹ orin o kapa inu wọ, o lu jẹdi l'alupa gbogbo abiyamọ nyọ ṣẹṣẹ. Eis ri i o roju, Orerẹ ri i o na'gbẹ bo'ra Ẹyi npa lẹmọ lodiẹsọ, ọrẹ ikoko, koṣemani awọn abiyamọ, ẹni araiye njijadu ra. O de ilu Ibo, o dọga o de ile Hausa, o d'ọba gbogbo Oniṣegun l'o sọ pe ko lẹgbẹ gbogbo ọmọde lo nfe ẹ fun ilera

100 KEKERE 2/6d 100 NLA 4s owo ọkọ lọtọ.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2 Ebute -Metta




## BẸẸ KAIYE

IBADAN—Iyawo Oyinbo ṣọja kan ni a gbọ wipe o fi igo ọti mẹta ṣe afọ'wọra ni Ṣọbu Kingsway, nilu Ibadan, ni awọn ọlọpa ba mu de iwaju adajọ.

A gbọ pe o sọkun pẹrẹpẹrẹ ninu ọpoti nigbati adajọ ke iori rẹ fun pọun mẹdogun tabi ẹwọn oṣu meji bi ko ba ri owo san.

Ọrọ re o.

# Afese Pa meje

Apa III

Okiki Afẹṣẹ pa meje bẹrẹ si kan kakiri aiye wipe Afẹṣẹ pa meje fi ẹṣẹ kan pa omiran, o wa di ẹru jẹjẹ si gbogbo awọn ti ko mọ ọ ri, gbogbo awọn omiran ti o gbọ iro wipe Afẹṣẹ pa meje fi ẹṣẹ pa omiran ti o buru-julọ, ẹru rẹ wa bẹrẹ si ba wọn.

Lojọ kan bi Afẹṣẹ pa meje ti nlọ, bẹni o ṣe pẹkirẹki pẹlu omiran kan, ẹru koko ba omiran na ko fẹ ki Afesẹ pa meje mọ ile on, o fi igboiya sọ fun u pe, ki o pa itu ọwọ rẹ ki on ri, bi on ba bori Afẹṣẹ pa meje on yio fi jẹ ama ba lon', ṣugbọn bi on ko ba bori ki Afẹṣẹ pa meje pa on.

Afẹṣẹ pa meje bere mu okuta kan, o wa bẹrẹ si ba omiran nasọrọ pe, bi on ba ju okuta yi yio wọ ọrun lọ. Nibiti o ti nsọ ọrọ yi lọwọ, o ju okuta sinu apo o mu ẹiyẹ oju soke bẹni ẹiyẹ ba gbọn idi gbu, o si fọlọ. Omiran na reti ki o pada wa balẹ ṣugbọn ko pada.

Kai! Omiran na dahun pe, eyini ko ṣoro ni ṣiṣe, ni iwon igbati iwọ kekere yi tile ṣee, o oyẹ ki emi na le ṣe. Nitori na o bẹrẹ mu okuta kan ti o tobi to ori enia, o ju u, sibẹ sibẹ, o tun pada wa balẹ. Afẹṣẹ pa meje bẹrẹ si daiyaja Omiran, bi iwọ ko le ṣe ọkan ti o ku agbari rẹ ni ngo fi fun fere loni.

A fẹṣẹ pa meje tun bẹrẹ mu okuta, o tun bẹrẹ si ọrọ sọ wipe bi on ba fi ọwọ fun okuta yi omi yio jade lara rẹ. Nibiti o gbe nsọrọ o ti ju okuta sinu apo o mu ekisa olomi bi o ti fun omi bẹrẹ si jade.

Ẹru ba Omiran yi o bẹrẹ mu akọ okuta kan o fun u ti o fi di atike mọ lọwọ. Omiran na kigbe wipe ha! *iru* enia wo niyi, ni Omiran na ba gbesi o si salọ fun Afẹṣẹ pa meje! Okiki Afẹṣẹ pa meje kan kakiri aiye lati Ariwa de Gusu ati lati Ila-Orun titi de Iwọ-orun gbogbo enia lo nfẹ mọ.

Afẹṣẹ pa meje rin titi o de ibikan, lo ba sun lọ fọnfọn. Ọkan ninu awọn ijoye ilu na wa npada bọ lati oko, nigbati o ri Afẹṣẹ pa meje o sare lọ rohin fun ọba. Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ okun fun ọgbọn ati imọ.

# Oro Iwuri Nipa Ologbe Jibowu

Bi enia ba wa loriyẹ ti koiti ku a ko ni mo riri iwa rẹ ni, ati bi ọla rẹ ti to. Sugbon bi oluwarẹ ba ku tan, ni aṣiri gbogbo iṣẹ ti ẹni na ti ṣe ni buburu tabi ni rere yio wa tu sode. E gbo ohun ti awon enia wi nipa ti Ologbe Sir Olumuyiwa Jibowu, Adajo agba ni ipinle Iwọ-orun.



ALHAJI TAFAWA BALEWA

Pẹlu ibanujẹ ni mo fi gbo iro ibanujẹ ti iku Sir Olumuyiwa Jibowu, adajo agba ni agbegbe Iwo-orun adanu na ki iṣe fun Iwo-orun nikan, bi koje fun gbogbo ijoba ilẹ Nigeria, ni pe Ologbe Jibowu jẹ okan ninu awon olupilẹṣẹ ijoba ilẹ Nigeria.

A ko ni tete gbagbe gbogbo awon iṣẹ ribiribi ti o ti ṣe larin wa. Ododo rẹ lo fihan fun gbogbo agbaiye pe, enia dudu to eni ti o le ṣe idajo ara won.






# Ijoba Fe Si Ilewe Berefutu

Lakoko ti ilewe Saint Peter wo lulẹ, ti o si pa awọn ọmọ ilewe, nigbana ni nwọn ṣe ofin pe gbogbo ilewe ti a ti kọ lojọ pipẹ sẹhin, ki nwọn wo lulẹ, ki nwọn si tun omiran kọ.

Nigbana ni nwon ti wo ilewe Breadfruit lulẹ nwọn si kọ ni petesi meta o si gba to egbaa ọmọ ile ẹkọ.

Ni agogo mẹrin irọlẹ ojọ Saturday 13th Oṣu June, 1959 ni Ọgbeni Aja Nwachuku yio ṣi ile ẹkọ titun ti Saint Paul's Berẹfutu (Breadfruit) Lati ma kọ ẹkọ ọlọfẹ nibẹ Gbogbo awọn ọmọ ti o si ti lo ukọ nilẹ ni yio lọ bẹrẹ ẹkọ ọlọfẹ nibẹ

MO NWA IYAWO FORI ṢỌPON

Ọkunrin arai ilu Griki kan ti o kowe sinu Igo ti o gbe ju sinu okun, pe bi o ba ṣe obinrin ni o ri ki o kọwe si on, ọkunrin ni eniti o ri Igo na. Aki igbe ọkunrin niyawo.


E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE

LỌSỌSẸ, O KUN FUN IROHIN ALADUN

Kere o!

Ati ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos. P. O Box 467

CABLES & TELEGRAM "ELETI - ỌFẸ LAGOS" Phone 23370

VOL. XI. NO. 627. SATURDAY JUNE 6 - JUNE 12, 1959


# Ojo Iku L'a Nd'ere Enia Ko Suwon L'aye

Ọjọ ti enia ba ku fi aiye silẹ ni aṣiri iṣẹ rẹ, iwa rẹ ati gbogbo ihuwasi-isọrọsi rẹ ni rere tabi ni buburu yio tu s'ode fun gbogbo enia ri. Bi oku fẹ ẹ, bi ko fẹ ẹ, ẹ o ri oju ọmọ oloku lode. Owe Yoruba kekere yi ni a fi ṣe ẹṣin wosika wa ṣẹ yi, nibi ṣoṣi, lori iku aitẹjọ airotẹle ti o wọle mu enirere lọ, Ọlọla Olumuyiwa Jibowu, Onidajọ Agba ni ipinlẹ Iwọ-Orun.

Ọlọla Olumuyiwa jẹ ijinlẹ enia ninu ẹgbẹ amofin (Lawyer) olododo enia ni iṣe, ko si ni ojusaju enia ninu iṣẹ rẹ, iwa ailabawọn wọnyi ni o gbe Jibowu de'po Adajọ agba ti o mu ki ọpọlọpọ awọn ọmọ wa le ma bọ si ipo adajọ nisisiyi.

Bi a ba ni ki a ma to " bi-enu-bi-enu, yio to aṣọ nihihun" ni ọrọ Ologbe Ọlọla Olumuyiwa Jibowu jẹ nilẹ Nigeria. Iku rẹ jẹ adanu 'pataki fun orilẹ-ede wa ti Ọlọla Ologbe Olumuyiwa jẹ ọkan pataki ti o fi iṣẹ rẹ gbe ilẹ Nigeria ga de'po ti a fi ngb'orun ominira wa nisisiyi, ti ọwọ gbigbona iku ko jẹ ki Olumuyiwa le f'oju ri.

A fi wosika wa yi ki Olotu ijọba Iwọ-orun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn isọngbe rẹ ku ajalu ọfọ iku Ologbe Sir Olumuyiwa Jibowu.

Ki Ọlọrun gbe si afẹfẹ rere.

# Sardauna Ilu Sokoto



Ọlọla Sir Ahmadu, Bello, Olotu ijọba Ariwa, nilẹ Oke-Ọya ti a nwo aworan rẹ yi ni o fi waya ranṣẹ si Ijọba Iwo orun wipe:
Mo gbo iku Ọlọla Sir Olumuyiwa Jibowu, adajo agba ipinlẹ Iwọ-orun lori irin abẹwo mi ni agbegbe Sokoto, mo wariri. Mo fi eyi ba ọ kẹdun iku Ologbe Jibowu ki iṣe adanu ipinle Iwo-orun nikan bikoṣe fun apapo ile Nigeria.
Ki Oluwa gbe si afefe rere.






## T'ỌKỌ-T'AYA JẸ OLU AJẸ D'ỌRUN.

AUCHI. Irohin kan wa wipe Ọkunrin kan, iyawo ati ọmọ rẹ ni nwon jẹ ọbẹ ti nwon fi *olu* se, ni o ba di ohun ti nwon fi ni lati gbe won lọ si ile Iwosan (Hospital) nilu Auchi.

A gbọ wipe lẹhinti nwon jẹ ọbẹ olu yi tan ni arun onigba-meji yi wọ, ti nwon nṣu ti nwon nbi. Nigbati ọwọ ko fẹ ka mọ ni o ba di ile Iwosan, nibẹ ni awon mẹtẹta gbe ku si.
Awon enia ni ero wipe boya majele ti wọ inu ọbẹ olu na ni o fa sababi iku to pa won. Nje lọwo onjẹ ajẹ d'orun, Oluwa rere gba wa.

## OWO ẸKỌ AWỌN ỌMỌ TOWA NILU OYINBO

EKO. Nipa iwe ẹbẹ kan, eyiti Candido Adenikẹ Afodu, kọ si adajọ kotu Ganran wipe, ki adajo na pa laṣẹ fun Oyinbo Aṣoju pe lati ma fi owo ranṣẹ si awon omo on Taiwo Kẹhinde ati Olu Da Rocha-Afodu ti nwon nkọ iwe lọwọ nilu Oyinbo. Adajo na si gba bẹ, o so fun Aṣoju na *wipe* gbogbo owo ti awon Banki ba fi ranṣẹ si awon omo na, ki nwon ṣe iṣiro rẹ siun ipin ti Adenike Afodu.

# Iya Oba lo Be Ile Kenya Wo



**Lasiko** ti iya oba Gesi da kan lo be ile Kenya wo, ibe lo ti ba ijoye kan pade ara ilu **Turkana**, ti o si gbowo lowo iya oba na.

**Iya oba** ni a nwo ninu aso funfun ti o de akete funfun ti o si wo bata funfun. Oloye **Losu ara** ilu Turkana ni o lo aso mo idi, ti o si fi aso funfun pakaja ti o si tun we **lawani**, oo ni a nwo ti o nki iya oba ninu ile Gomina nilu Narobi.

## Jesu Oyingbo Nse Wasu

Opolopo ti oro yi soju won yio ranti akoko kan ti okunrin kan nse waasu ... ode ti nwon npe ni Jesu ... Ikhin re ni opolopo Jesu ti dide gegebi Jesu Kalaba, ati Jesu Ijebu-Ode.

Nisisiyi ni okunrin miran tun sese dide ti nwon npe ni Jesu Oyingbo. Die ninu oro ti a gbo pe o so niyi:-

Emi ni Jesu Kristi eni ti a ti so asotele re wipe o tun npada bo wa lori ekeji. Emi na niyi, mo ti pada de, enikeni ti o ba si gbo mi gbo, ki yio segbe, yio si ni iye ainipekun. Mo ti de nisisiyi lati pese awon Olododo fun idajo.

Mase fi oro mi yi se erin rin, bi oro alawere enia, nitoripe emi to soro yi, eni mi pe.

Jesu ti Nasareti ni omo ehin mejila sugbon edegberin enia ni omo ehin ti emi.

Oju gbogbo won ti la si ododo oro na wipe, emi ni Jesu.

Abi mi ni ilu Oba, lojo keta osu October 1915, ni Ijebu-Ode mo si kowe ni ilewe St. Saviour. Mo bere ise ni Post Office, mo si fi ise sile ni odun 1948, lati bere ise ti ara mi.

Obinrin meje ni mo fe ni iyawo mo si bimo pupo ni odun 1951, ni mo gbo ipe. Ko nse wipe mo mo iwe tara, sugbon nigbati a ba fi awon apa inu Bibeli han mi, nigbana ni mo ni gbogbo pe Olorun pe mi. Afi agbara wo eni lati ma se iwosan ati lati ma gbani kuro lowo emi esu.

Awon omo-ehin re bi Ogbeni Olufemi Olugbola ati Jonathan Fadina bo s'ode, nwon si jeri si oro Asiwaju won, Ogbeni Emmanuel Odumosu ti nwon pe ni Jesu Oyingbo yi.

## OMI YA WO ILU ACCRA

ACCRA. Ninu owara ojo to ro koja lo yi, ojo na po jojo nilu Accra tobe ti agbara ojo na fi kun akunya wo ilu. Awon oko igbaja ti awon Aganyin fi nko eru lo sinu oko ni nwon fi nse igbala fun awon enia ti omi ka mo.

Omi kun akunya bo okan ninu awon opopo ona moto tobe ti awon moto ko ri ona gba koja ni gbangba (square) kan ti nwon npe ni Kwame Nkrumah circle.

Awon olopa so wipe opo awon enia lo fi ara pa ninu gbagba-gbugbu oji na ti gbogbo ile bere si yo awon enia subu, opolopo ile egbe, ile gbigbe ogba ere ale ni oji na wo lule.

Awon Panapana ati awon olopa se iranlowo fun awon enia. A tile gbo pe iru eyifu ojo na koiti ja lati odun 1938.

## NWON NJA OKO AGTION GROUP LOGUN

ILORIN. Idagiri sele ni Abule Anigeri lagbegbe Molete ni ose to koja lo yi nigbati awon ara Paku, bogunwa si Molete, nwon si bere si ja oko omo egbe Action Group ti o wa nibe logun agbo pe awon omo egbe N.P.C. lo tise na.

Pelupelu nigbati awon enia na mbo, awon nla, awon njo, nwon si nkorin ogun. Loya kan wa kowe si adajo wipe, awon eniti ati fi san ti nwon nloja oko logun lakoko ki nwon ma se rojo niwaju Alikali nitoripe o ye wipe ki a so fu nawon enia na wipe idi ni a nso ifa mo, ati wipe on fe pe ki a gbe ejo na wa si kotu adajo nibiti ofin gbe dun'le ki a ba le ri oju ejo na.

## OWO ISE LOYA JE EGBAA MEFA POUN NINU OWO DA ROCHA

EKO. Nipa oro ejo ogun Ologbe Candido Da Rocha ti o fi sile fun awon omo re eyiti o tun pada dijagbon ti ede oyede ko wo arin meji awon omo Ologbe na tobe ti nwon ro si eto won pe ayafi kotu ni o le pari ejo na fun awon.

Owo sile sandi ti baba won ni ni ipamo ninu B.W.A. Ltd je Oke medogbon poun. Ninu owo yi ni Adajo ... pase wipe ki awon omo Oloko gba egbaa mefa Poun ninu ogun baba won lati fi sanwo ise ti loya yio se fun won ninu ejo yi titi yio fi pari.

